# IWOSAN ẸLẸMI ÈṢÙ ARÁ GÁDÁRÀ

## Marku 5:1-20

### ẸKỌ 79 – FUN AGBA

**AKỌSORI: "Ẹniti o ba si tọ́ mi wá, emi kì yio ta a nù, bi o ti wù ki o ri" (Johannu 6:37).**

**I Irin Ajo Aanu Kristi**

1. Jesu rekọja si apa keji okun, Marku 5:1; Luku 8:26
2. Ọkunrin kan ti n fẹ́ iranwọ tọ Jesu wá o si fori balẹ fun Un, Marku 5:2-6; Luku 8:27, 28; Matteu 9:13; Luku 19:10
3. A paṣẹ fun ẹmi aimọ́ naa ki o jade kuro lara rẹ̀, Marku 5:7, 8; Luku 8:29; Marku 1:27

**II Ọta Gbogbo Eniyan**

1. O hàn gbangba pe awọn ẹmi eṣu ni awọn adaniloro wọnyii, Marku 5:9, 12; Luku 8:30; Jobu 1:7; Efesu 6:12
2. A rẹ legioni awọn ẹmi eṣu naa silẹ a si sọ agbara wọn di ofo niwaju Ọmọ Ọlọrun, Marku 5:10; Luku 8:31; Matteu 28:18; Filippi 2:9, 10
3. A lé Satani jade, Marku 5:11-13; Luku 8:32, 33; 4:35, 36; Kolosse 2:9, 10; Matteu 8:32; 17:18; Iṣe Awọn Apọsteli 5:16; 19:11, 12
4. Pẹlu aanu ti Jesu fi hàn ni ojukoju bayii, awọn eniyan wọnyii tun bẹbẹ pe ki O kuro ni agbegbe wọn, Marku 5:14-17; Luku 8:37; Matteu 8:34; 2 Timoteu 3:8

**III Iyipada Nipa Oore-Ọfẹ Ọlọrun**

5. Iyipada ọkàn naa n sọ irisi ode ara di titun, Marku 5:15, 19; Luku 8:35; 2 Kọrinti 5:17; Titu 3:5
6. Ọkunrin naa fẹ lati maa ba Jesu gbé, Marku 5:18; Luku 8:38; Orin Dafidi 73:25
7. Jesu yan iṣẹ fun ará Gadara naa lati ṣe, Marku 5:19; Luku 8:39; Orin Dafidi 107:2: Matteu 10:32, 33; Romu 10:10; Iṣe Awọn Apọsteli 4:20; Isaiah 62:6
8. Ẹri iṣẹ iyanu ti Jesu ṣe ya awọn eniyan lẹnu, Marku 5:20; Matteu 15:30, 31; Luku 4:37

## ALAYE

**Wiwá Awọn Ti O Nù**

Ọlọrun kò ti i dẹkun lati maa wá ọkàn awọn eniyan kiri. Ọmọ Ọlọrun kò lọra lati fi awọn mọkandinlọgọrun silẹ lati rin irin ajo jinna réré, bi o ba gbà lati ṣe bẹẹ, ki O le mu ọ̀kan ṣoṣo ti o nù pada bọ̀ sinu agbo ni alaafia (Johannu 10:11; Luku 15:4-7). Iwe Mimọ́ sọ pe Jesu de "lati wá awọn ti o nù kiri, ati lati gbà wọn là" (Luku 19:10). Nitori eyi ni Jesu ṣe lọ si ilẹ awọn ara Gadara ni odi keji okun Galili. O ti fi owe kọ́ awọn eniyan ni ọpọlọpọ ẹkọ, ṣugbọn bi ilẹ ti n ṣú lọ, O sọ fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ pe wọn yoo lọ si odi keji okun. Boya awọn ọmọ-ẹyin ti n rò ninu ọkàn wọn lati lọ sinmi nibi kan, ṣugbọn Jesu ni ohun miiran lati ṣe. Oun mọ pe ọkunrin kan wà ni odi keji okun ti o ni wahala -- ọkunrin ẹlẹmi eṣu, ẹni ti o wà ninu ibanujẹ labẹ ipọnju ati idè Satani. Bi ẹlẹmi eṣu naa ti n rin kiri ni bèbè okun ninu okunkun ati otutu ọganjọ oru yii, o ṣe e ṣe ki ọkàn rẹ̀ maa poungbẹ fun igbesi-ayé ti o sàn ju eyi ti o n gbé yii lọ.

Bi Jesu ati awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ ti n rekọja si apa keji okun iji lile bẹrẹ si jà, igbi omi si ya wọ inu ọkọ. Awọn ọmọ-ẹyin ké pe Jesu Ẹni ti O bá afẹfẹ wi ti O si dá igbi duro. Ẹnu yà wọn si ohun ti wọn ri gẹgẹ bi ẹnu ti ya awọn eniyan nigba ti Jesu tun ba iji lile ti o jà ni igbesi-ayé ẹlẹmi eṣu ara Gadara wí.

**Iranwọ fun Alainiranwọ**

Nigba ti ọkọ wọn gunlẹ si ebute, ọkunrin kan ti o ni legioni ti ẹmi eṣu pade Jesu. Ẹṣẹ ti ra a niye. Agbara ẹmi buburu ti bori, o si n ṣakoso ọkunrin naa to bẹẹ ti awọn eniyan ti n fẹ ṣe iranwọ fun un fi ni lati de e ni ẹ̀wọn, ṣugbọn o maa já ẹwọn naa wẹ́wẹ́. Oun a lọ si iboji a maa fi okuta ya ara rẹ̀ a si maa kigbe tọsan toru nitori irora nla. Boya eniyan le ro pe ti ọkunrin yii ti kọja ti ẹni ti o tun le ri iranwọ gbà, ṣugbọn Jesu jẹ iranlọwọ alainiranwọ, ati ireti fun awọn ti ko ni ireti. "Enia li eyi ṣoro fun, ṣugbọn fun Ọlọrun ohun gbogbo ni ṣiṣe" (Matteu 19:26).

Ọkunrin naa ri Jesu ni okeere, o sare tọ Ọ wá, o si foribalẹ fun Un. Jesu si bá awọn ẹmi aimọ́ naa wí O si paṣẹ pe ki wọn jade kuro lara ọkunrin naa. Awọn ogunlọgọ ẹmi aimọ́ wọnyii (wọn pọ̀ to bẹẹ ti a fi pe wọn ni Legioni) di alailagbara niwaju Jesu. Nipa aṣẹ Rẹ̀ wọn **ni lati** fi ọkunrin naa silẹ, ati nipa iyọnda Rẹ̀ wọ́n wọ inu awọn ẹlẹdẹ lọ, agbo ẹlẹdẹ si tú pùú wọn lọ parun sinu okun. Nipa ọrọ Jesu ọkunrin naa di ominira a si wò ó sàn lara ati lẹmi.

**Ohun Ini Wọn Ká Wọn Lara**

Nigba ti awọn ara ilu naa gbọ́ ohun ti o ṣe

lẹ wọn yara tọ Jesu wá. A ko ri ka pe inu wọn dun si iyipada ti o dé si ẹlẹmi eṣu naa, ọkunrin ti gbogbo wọn bẹru ti igbe rẹ̀ si n dáyà fo wọn ni gbogbo oru. Wọn ko ṣiro pe anfaani ni iwosan rẹ̀ jẹ fun wọn pẹlu, ni ti pe ẹni ẹ̀rù jẹ̀jẹ̀ fun gbogbo ara ilu ti di ọmọ ibilẹ rere bayii. Bibeli ni wọ́n bẹ̀rù. O le jẹ́ pé wọ́n bẹru nitori wọ́n padanu ohun ini wọn -- nipasẹ eyi ti wọn ni ipese fun igbesi-ayé wọn ojoojumọ.

Ni ọpọlọpọ igba ni awọn eniyan maa n gbe oju fo awọn iṣẹ iyanu Jesu nitori wọn fi ọkàn si awọn ohun ini nipa ti ara ju awọn ohun ti ẹmi. Wọn tilẹ le wo igbesi-ayé ti a yí pada nipa agbara nla Ọlọrun ki wọn si kuna lati ṣe akiyesi iṣẹ iyanu naa ti o ṣẹlẹ. Ẹ má ṣe jẹ ki a kuna lati fi iyin ati ogo fun Ọlọrun fun iṣẹ iyanu wọnni ti O ti ṣe ni igbesi-ayé wa ati ni ayé awọn ẹlomiran, ki awa paapaa má ṣe ti ipa ọrọ tabi iṣe sọ fun Olugbala pe ki O lọ kuro lọdọ

wa gẹgẹ bi awọn eniyan Gadara ti sọ fun Un. Dajudaju awọn miiran wà nibẹ ti wọn n fẹ imularada lati ọwọ Jesu ṣugbọn awọn eniyan ṣe idena riri ibukun ti ẹmi ati ti ara gbà nipa bibẹ Jesu pe ki O lọ kuro ni agbègbè wọn.

**Agbara Ẹjẹ Naa**

Iriri iyanu ti igbala ninu eyi ti a "tún enia bi" (Johannu 1:12, 13; 3:3-21) ti o si rekọja lati inu ikú bọ́ si iye, jẹ oore-ọfẹ ti a fi Ẹjẹ Jesu Ọmọ Ọlọrun rà fun wa lori agbelebu. Igbala jẹ iriri, ti a n rí lẹsẹ kan naa ninu eyi ti a gba eniyan kan kuro labẹ akoso eṣu lati ni idapọ pẹlu Jesu; a si le ri eyi gbà nipa titọ Jesu wá pẹlu irobinujẹ ati irora ọkàn, ki a kọ ẹ̀ṣẹ wa silẹ ki a si yi pada patapata si I. Ẹjẹ Ọdọ-Agutan Ọlọrun ti a ti ta silẹ naa n wẹ gbogbo ẹṣẹ nù kuro ninu ọkàn ti o ba ronupiwada (Ka 1 Johanu 3:8-10).

Ni ori kẹtalelaadọta (53) iwe Isaiah, ki i ṣe ileri Olugbala ati Oludande nikan ni a ri kà ṣugbọn ti Oluwosan lati Ọrun pẹlu. Iwosan nipa agbára Ọlọrun wà ninu eto irapada, nitori ọgbọn Ọlọrun ti pese fun gbogbo kò ṣe e má ni awọn eniyan Rẹ̀. Ninu ikú Jesu lori agbelebu, O ti ra iwosan fun ọkàn ati ara. Ninu Ẹksodu 15:26 Ọlọrun sọ gbangba pé Oun ni OLUWA ti O n mú awọn eniyan Rẹ̀ lara dá; otitọ si ni ileri Rẹ̀, ki i yí pada (Numeri 23:19; Isaiah 40:8; 1 Peteru 1:25). Agbara Ọlọrun kò dinku rara; Jesu ọkan naa lana, lonii ati titi lae (Heberu 13:8).

Ọlọrun sọ kedere ninu Ọrọ Rẹ̀ pe ki a gbẹkẹle Oun nigba gbogbo ki a si nireti ninu agbara Ẹjẹ Rẹ̀ ti i mu ni larada. A sọ fun ni ninu Jakọbu 5:13-15 ohun ti o yẹ ki a ṣe gan an nigba ti aisan ba kọlu wa. Egun wà lori ẹni ti o gbẹkẹle eniyan ti o si fi ẹlẹran ara ṣe apa rẹ̀ (Jeremiah 17:5), ibukun si wà fun ẹni ti o gbẹkẹle Oluwa (Jeremiah 17:7).

**Ọ̀tá**

Ọta kan wà titi di oni-oloni ti o n sa agbara lati mu awọn eniyan fà sẹyin kuro lọdọ Ọlọrun, o n fi idè ẹṣẹ dè wọn mọlẹ bi ẹ̀wọ́n ti o si n sọ wọn di alailagbara bi ọkunrin ti ẹmi eṣu n dá loro yii. Satani ni ẹni naa ti o n dù ú lọnakọna lati sọ awọn eniyan di ẹrú ẹ̀ṣẹ, ṣugbọn Jesu de, "lati ṣe awotán awọn onirobinujẹ ọkàn, lati kede idasilẹ fun awọn igbekùn, ati iṣisilẹ tubu fun awọn ondè" (Isaiah 61:1). Ọlọrun fẹ ki awọn eniyan gba Ọrọ naa gbọ́, nigba naa ni wọn yoo to di aṣẹgun nipasẹ Jesu ti o ni gbogbo agbara ni Ọrun ati ni ayé.

**A Fun Un ni Aṣẹ**

Ifẹ ọkàn ọkunrin ará Gadara ni pe ki oun maa ba Jesu gbé, ṣugbọn Kristi n fẹ ẹlẹri kan ni ilu naa. Ọkunrin yii, ẹni ti i ṣe iṣẹ iyanu ti ko fara sin, gba aṣẹ lati pada lọ si aarin awọn eniyan rẹ̀ ki o si maa jẹri si titobi agbara Ọlọrun. Oun le rán wọn leti iru eniyan ti oun ti jẹ́ tẹlẹ; bi ẹ̀ṣẹ ti pa iye oun rẹ́ ti o si gba ohun rere gbogbo sọnu lọwọ oun; ati pe Jesu dé, Ó bá awọn ẹmi ẹ̀ṣù naa wí, Ó si lé wọn jade kuro ninu oun. Nigba naa ni oun tó ni alaafia ati isinmi ninu ọkàn. Ọna kan ti o le gbà dupẹ lọwọ Oluwa fun ohun ti O ṣe ni pe ki o gbọran si aṣẹ lati maa jẹri si iyipada nla ti Oluwa mu wa si igbesi-ayé rẹ̀. Bi o ti n ṣe eyi, ni ẹnu n ya gbogbo eniyan.

**AWỌN IBEERE**

1. Iru ipo wo ni ọkunrin ará Gadara naa wà?
2. Ki ni ṣe okùnfà ipo buburu yii?
3. Ki ni ohun kan ṣoṣo ti o le mu iyipada wa fun un?
4. Apẹẹrẹ iru eniyan wo ni ọkunrin yii jẹ́ lọjọ oni? Ki ni ọna abayọ?
5. Iru eniyan wo ni awọn ará Gadara?
6. Ki ni ṣe ti ibeere wọn yàtọ̀ si ti ọkunrin ti o ti ni ẹmi eṣu ti a wosan?
7. Iru iṣẹ wo ni a rán an, ipa wo ni iṣẹ naa si ni lori awọn eniyan naa?